AWON ALAKORI FE JA OKU L'OLE NI LALUPON

Drink Coca-Cola
STANDARD SIZE 4D
NEW KING SIZE 6D
See that you pay the correct price.

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO ṢE WI'L'EJO

6th & 7th BOOKS OF MOSES
LEDE YORUBA
15/
A LE RI IWE YI RA NI OSHODI COMMERCIAL SERVICE
36, KING GEORGE AVENUE YABA
ATI NI
IDIKAN ROAD IBADAN

VOL. IX No. 542 ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, OCTOBER 19, 1957. KOBỌ MEJI (2)

# Awọn Alakori Fe Ja Oku L'ole

LALUPỌN Oniwe irohin wa kan sọ wipe ni ati ojọ ti on ti de ile aiye, on ko ri ibiti awọn ole ti npiyẹ ni ọsan ati l ru gẹgẹb ti Lalupọn ni Odo Ọba ribi ri. Ọjọjumọ ni wọn nra baba bi ẹiyẹ Aṣa ti o fẹ gbe ọmọ adiẹ. Omiran wa lati gbe ori tabi ọwọ ninu awọn oku ti ọkọ Reluwe pa lati fi ṣe ogun. Ẹlomiran nwa owo ti awọn oku ra di mọ'ra lati ja mọ wọn lara.

"Ṣe Ijọba lo wipe awọn ko l' wọ wọn jade". bẹni ikan ninu awọn alakọri na nwi nigbati awọn ṣoja ati ọlọpa ti wọn fi ṣọ ibẹ nle wọn lọ. A le Jugbẹ ma ni ti oru ijẹrin, o si to ẹmeta ti awọn olori buruku ọlọṣa na gbidanwo lati m'okun ninu ere lati ṣe iṣe aidara yi

A gbọ wipe nigbati awọn oṣiṣẹ gbe ikan jade ninu awọn wagonn ti o ri si odo na, agbọri ọmọ en'a loku ti nwọn nju sinu posi. Ọgọ'ọ ni owo ti wọn ri ko ninu ẹru ati ara wọn 'Ayiluka' Eleti-Ọfe ni o ri ọpọlọpọ owo yi ti awọn ọlọpa Ibadan nṣa ninu orun ni Barcke wọn.

## Adepehin Di Oniyawo Mo yo!

EKO. Kosi botiri ni irohin igbeyawo ti Ọgbẹni wa Pẹhin Martins, Ọga ile iṣẹ awọn Olutaja Koko (Marketing and Export) ṣe laipẹ yi.

Orin Ologbe Bẹghaji yi ni a fi ki ọrẹ wa, Ọgbẹni Adepẹhin Martins ku inawo ọjọ

Oyin ororo, iyawo o,
Oyin ororo, aṣebe l'odun to o, Oyin la ẹ O o,
Ororo iyawo o, Oyin ororo.

Ki Oluwa i ọwọ iyawo b'osun o. Amin.

wa sile aiye.

Irọ nla-nla, Irọ, Irọ pataki-irọ-irọ ni awa Eleti-Ọfẹ gba eyi si o. Olotu.

## Ategun gbe Ilewe Ahmaddiya lo

EKO Ọrọ ko dun, nigbati irohin gbojikan kakiri ilu Eko, wipe, atẹgun gbe panu ilewe kan lọ lasiko igbati ojo arọ lọwọ ati wipe ogiri ilewe na ya lulẹ pẹlu.

Hẹn, hẹn, hẹn, nigbogbo awọn ara Eko lọkunrin ati l'obinrin ti mọ wọn nlọ silewe na ba tẹsẹbẹ ṣokoto, o di Ṣokoto, awọn obinrin gan iborun wọn leti, rẹrẹ, o di ilewe na, ni ọjọ Alamisi 17th oṣu October 1957.

Lẹhin ti riwo-riwo rolẹ tan, ni a gbọ wipe panu ilewe na lo si kuro, ti atẹgun si gbe fo lọ si adugbo miran ati wipe ogiri ti nwọn wi, ko tilẹ ya lulẹ rara, a ko si gbọ wipe jamba ṣe ẹnikan.

## Okete Soro Ni Abeokuta

ABẸOKUTA. Irohin agbayanu ti a gbọ ni wipe Okete kan ti o in Pakute ti nwọn dẹ sinu igbo, sọ wipe ki Onipakute maṣe lu on pa, labari ọrọ pataki ni on mu

# Awolowo Gba Alhaji Balewa Ni Alejo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alhadji Tafawa Balewa, ti o nṣe Alakoso Ijọba ilẹ Nigeria on lo dakan lọ si Ibadan lati lọ ba Oloye Awolọwọ jọ sọrọ ododo ọrọ kan.

Awọn ijoye Ijọba agbegbe Iwọ-orun ti o wa ninu igbimọ ọrọ ti nwọn jijọ sọ na ni Oloye F. R. O. Williams ti o nṣe Alabojuto ofin ati Alakoso Ijọba ibilẹ ti agbegbe Iwọ-orun ilẹ Nigeria (Minister of Justice and Local Government.) Oloye Anthony Enahoro ti o nṣe Alabojuto ibudo Ijọba Iwọ-orun (Minister of Home Affairs) wa nibẹ, Oloye C D. Akaran ti o nṣe aṣoju Premier Oloye Awolọwọ lo ṣikẹrin wọn gba Alhaji na ni alejo.

Ko da bi ọrọ na ti ṣe pataki to ninu ag'ala igbadun Awolọwọ ni nwọn gbe joko jomitoro ọrọ na pẹlu ẹrin ati faaji, bi nwọn ti pari ọrọ na tan ni Alhaji na ti pada si Eko.

# Awon Ara Ilu Osi Ko Oba Won

ILORIN. Irohin ti a gbo ni wipe Ogbeni Afolabin ti nwon fi joye Olosi ilu Osi ti o si tun je wipe, on kan ni loni lati se alaga ninu igbimo ati Ijoko ibi ate idajo, ni awon enia pariwo le lori lasiko yi nigbati o fe wo ibi idajo lati wa bere si dajo.

Nigbati won si se abere ohun won, kilofa ti nwon fi se be? Idahun ti nwon mu wa ni wipe awon igbimo Alase ibile Ilorin ko ba won so tele wipe awon ti yan enia ti y'o dipo Ologbe, oba Olosi ti o waja, ayafi bi awon ti ri Ezekiel Afolayan ti o wipe on fe joye alaga igbimo.

Nwon si tun bere wipe bawo ni oro na tise ri be? Nwon so pe awon omode meji Afolayan ti o ni awon afobaje merin gegebi alatilehin, ati Olorukoba ti o ni awon afobaje meta ni alatilehin, ni nwon jijo ndu oye oba na mo ara won lowo, sugbon awon afobaje ko ko sori enikan.

Ayafi bi Ogbeni Afolayan ti de wipe, nwon ti fi on je oye oba Olosi ni Ilorin, Bawo ni Igbimo Ilorin tise ni lati fi o joba lori wa ki a ma mo. Ajeji ha l' wa ilu ki Onile ma mo? Bawo ni e ti se fe ki ilu toro nigbati enu awon Afobaje ko jo ti ara ilu ko si mo? Idi oro re o.

# Ajele Ba Igbimo So Ododo Oro

ILORIN. Ninu igbimo alase ibile Ilorin nibe ni Ajele agba, Ogbeni J. B. Davies ti ba awon ara Ilorin soro nigbati awon kan atako wipe owo ori, ni sisan, ko to si awon.

O so wipe ko si igbimo ilu kan ti o le duro bi ko ba si owo ori. Gbogbo ilu ati awon enia inu re, lo nfe ilosiwaju, ki ilu ba le dara gbogbo enia lo si nfe owo ati ekunwo pelu. Nje bi ko ba si owo ori, kini ao fi se? Olorun oba nikan soso lo le se nkan laisi iranlowo owo. Nitorina bi e ba nran awon enia lowo pe ki nwon mase sanwo ori, ko dara rara.

Ohun, ti o dara ni, ki e ma fi ko awon enia lati san owo ori won, nitori awon ohun mere-mere ti a ba muwa si ilu, owo lo paa.

Alaiyeluwa, oba Ilorin Mallam Abudu Kadiri lo se alaga igbimo na, on lo si fi ase si iye owo ti igbimo na yio na fun odun 1958–1959.

## Alo o, Alo

**1 Lagunrege oba Layilo Lafakale oba Layilo Labolorunduro oba Layilo, meta l'a npa, meta l'a nja! Kini nje be?**

**2 Okun nho ye e, osa nho ye e, gaga eran kan ko jeki nwon pade. Kini nje be ?**

# Kini Itumo Capitalist, Communist ati Socialist

Olotu,

Nigba gbogbo ni a ma ngbo lenu awon omo'we wipe, awon egbe kan wa ti nwon npe ni Capitalist, Communist ati Socialist; awon oro nwonyi ko ye awa ti o nka A B D. GB Inu wa y'o dun jojo bi Olotu Iwe irohin Eleti-Ofe ba le la awon nwonyi ye wa.

Emi ni Joseph Alalade Idahun

Capitalist- Awon egbe kan wa ti nwon gbagbo wipe owo la fi nse aiye, laisi owo ko si si nkan ti enia lese. Nwon si tun npe Olowo be pelu.

Communist- Awon egbe kan tun wa ti nwon nigbagbo wipe, ile aiye fun igba die ni, ohun kohun ti enikan ba ni pupoju, ko nse on ni kan soso lo ni lati lo ati olowo ati talaka, bakanna ni won.

Socialist- Awon egbe kan tun wa ti nwon gbagbo wipe gbajumo lo laiye ko si nkan ti nwon le se ti nwon ko ni mu je gbe.

OLOTU




## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun German to şeşe de, fun oniruru aisan tokuta tobinrin. Tete wa ra tire, k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

## E ma Ka Iwe Irohin Eleti Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re

## Awon ara Ogere fe ko oba won

OGERE Irohin ti o sese de eti gbo wa ni wipe awon ara ilu Ogere dide si oba won, Alaiyeluwa Legusen keta, oba ilu Ogere lati le kuro lori oye oba ati wipe awon enia na ara ilu Ogere, yio mu oro na to Ijoba Iwo-Orun lo lati ba nwon gba ade kuro lori oba na.

Pantiwa! kini oba na kuku fi se awon ara ilu re tobe ti nwon se fe lo ese giguu fun u bayi? Esun ti a gbo pe nwon fi sun oba na ni wipe, o nni won lara, ati wipe oba na ko fe fara mo eyiti igbimo ba se, ayafi ti inu re, ko si fe tele ilana ofin ti Ijoba Iwo-Orun fi lele nigba gbogbo lo si ntako asa ibile Ogere.

Rogbodiyan na sele leri Poun mokanla ati sile-kan, owo ti Awo Osugbo bu fun owo oku kan ti oje omo Awo. Ninu odun 1950, awon Igbimo Loba-Loba, ati igbimo egbe omo Oduduwa ba won da si oro edekoyede to wa larin oba Ologere ati awon enia, re oro na pari, nwon si bo mo'e,

Sugbon ni kete ti nwon pari ija na tan ni edealyede miran tun be sile larin oba Ologere ati awon ena re, eyiti o nja ranyin nile titi di oni.

## Ara Bassey Kole

Irohin ti a gbọ ni wipe Amodi Ayọkẹlẹ kọla Hogan Bassey, gbogbo eto ti o ti ṣe silẹ ko ni le bọ si mọ ṣugbọn eyi ko diwo ati wa sile rẹ.



Ẹni ti o nṣiṣẹ kakiri ode nmu Ovaltine

nitoripe Ovaltine nfun ni ilera ati agbara lati ma a fi ṣe awọn iṣẹ rẹ pataki. Ovaltine ni onjẹ pataki ti ara rẹ nfẹ lati le fi rọpo ohun ti oba ti lo l'ọsan kọja. O nfun ni ni ọpọlọpọ agbara ati okun ti o le ta aisan l'aiya.

OVALTINE

Fun agbara ni gbogbo ọsan

# ELETI QFE
A-NJU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI – QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. IX. NO. 542 LAGOS, SATURDAY OCT. 19 1957

## E Fiyedenu. Enyin Onise-Ale

Qrq awqn onisę alę pęlu igbimq Town Council se edi ohun ti akole mojukuro, o si yę ki a şe arqwa fun awqn enia wa ti nwqn ję onisę-alę na (Night-soil removers) lori ede-aiyede to te sile larin igbimq Town Council pelu awqn enia wa na.

Ohun ti a fe ki awqn enia wa ti nwqn je Onişe-ale wqnyi mq ni wipe işe wqn je işe anfani ilu, ki a mu ti wipe, nwqn ngba owo kuro, aitoripe bi ko ba si ti wqn, alafia ilu di eru amijeje fun gbogbo eniti o ngbe ilu.

Nitorina ni a şe ke si awqn Onişe-ale, ki nwqn fiyedenu, ki nwqn maşe gbq ti awqn atanije enia ti nwqn nwa owo si apo ara wqn lati ma kq wqn wipe ki wqn maşe şe işe wqn gegebi o ti tq ati bi bi o ti yę. Bi eniti ba nşe işe ti o je anfani ati alafia fun ilu, daju-daju Oluwa Olodumare yio ma rq'jo ibukun s'ori oluware.

Nitotq ni owo ję ohun pataki şugbqn ibukun Oluwa ni o ju ohun gbogbo lq.

E fiyedenu o

## ANFE ASOJU

A nfę Aşoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Qfę lati fi kun awqn Aşoju wa ni awqn ilu ti a daruko ni isalę wqnyi:-

Abęokuta, Ijębu Ode, Ijębu-Igbo, Ile-Ifę, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kqwe si Olotu Iwe Irohin Eleti Qfę, 28, Kqsqkq St, Lagos.

## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamq ę wa ra QMQRELA o dara pupq fun awqn qmqde.

Ama ję ki qmqde ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orişirişi arun miran ti o ma mba qmqde ja ni asiko ehin. Qpqlqpq abiyamq lo ti lo egbogi yi fun qmq wqn ti wqn si sq wipe o dara pupq fun awqn qmqde

QMQRELA BABY MIXTURE

(Şile Meji Abq 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lqdq

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10 VICTORIA STREET, LAGOS.

## Irin'ke-rin de Qmqba Gesi Nile Nigeria



Irohin ti a gbq nipa irin lati de ilu Qmqba Gesi ti o mbq nilę Nigeria ni eyiti a to sisalę wqnyi:-

Nov 12th 1957-Qmqba na yio ba qkq ofurufu kuro ni ilu Oyinbo.

,, 13th-yio gunlę si Ikeja ni agogo męwa qjq yi yio ba męto lq sile Gomina. Ni agogo męrin abq irqlę, awqn ęgbę Girl Guides yio lq jo fun qmqba na sile Gomina. Ni agogo męfa koja işeju mędogun, awqn Oniwe Irohin ati Olotu ęrę asqrq magbesi yio lq ba qmq qba na sqrq.

,, 14th-Ni agogo męsan koja işeju mędogun, awqn ęgbę Ologun ti obinrin ti awqn npe ni Red Cross yio jo fun qmq qba na ni ibudo wqn ni Yaba. Lagogo męwa abq, Qmqba na, yio lq bę awqn Oyinbo ti o nşe iyawo awqn Ologun wo ni Ago wqn ni Yaba. Ni agogo mejila yio lq si Apapa, yio bę awqn Amqna wo (Nigeria Signal Squadron).

,, 15th-yio kuro ni Eko lq si Enugu niha Ila-Orun ilę Nigeria. Yio lq si ilu Onitsha ni qjq keji.

,, 18th-yio ti Enugu lq si Ibadan, On ni yio si şile Ifowo-pamqsi (Cooperative Bank Building) ni agogo męwa alę, ni awqn Gbajumq ilu Ibadan, yio lq jo fun qmqba na.

,, 19th-Awqn qmq ilewe yio lq ki qmq qba na; ni agogo mękanla, yio lq şe eto fun awqn qmqwe nile Ękó University Ibadan ati ni agogo marun irqlę Olośe Awolqwq yio şe ase fun qmqba na.

,, 20th Qmqba na yio lo ki agogo męsan to lu lati lo fi qja nla re han ninu ile 'gbimq Ibadan awqn Sqja yio si şe ęyę fun. Ni agogo mokanla abo koja yio şi ibudo ęgbę Ologun obinrin ti a npe ni Red Cross si Ibadan Yio ba Qkq reluwe lo si Ilorin

,, 21st-yio si ilewe kan ti nwqn npe ni Queen Elizebeth Girls Secondry School.

Lęhin ti o ba kuro ni Ilqrin yio lq si awqn ilu nwqnyi Kaduna, Zaria, ati Kano, lati ibiyi ni yio ti ba qkq ofurufu pada siilu oyinbo.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo ęnyin Aşoju Iwe Irohin wa nilę Yoruba, l'oke Qya, nilę Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe ęnikęni ti ko ba fi owo wa ranşę ki oşu to pari ao kq oruko rę fun Lqya Eleti-Qfę, ao ba şe ejq ao si gba owo ire ęsa lqwq rę,

OLOTU.

# AWON ALAIYELUWA GBA ISINMI



Awon omoba okunrin ati obinrin ni a nwo ninu aworan yi nibiti nwon gbe nsere "Oko-nrokun janyin-janyin ko" ninu oko Balmoral Castle, nibe ni Prince Philip. ti Ise baba won ti mba won nfi ese te igi patako ti nwon fi nsere na, Alaiyeluwa Oba obinrin si duro nworan won.

Awon Alaiyeluwa lo se abewo oko ati ero to nis'gi ni Balmoral Castle ni ilu Scotland ni asiko isinmi won.


**Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS**

*Read this list of popular titles*

JZ 6077-Omosola Savage/Igba Laiye
" 6078-Aiye Akamara/Iwa Rere Leso Eda
" 6079 Gbo Adura Wa Baba/Irele Lo Laiye (Rosey Show Mambo Orch)
" 6080-Gba Wa Lowo Ota/Iberu Oloru S. O. A. Ladipo and His Koranic Group
" 6082-Ola ne Lo Laiye/Feso Jaiye
" 6083-Shogbola/Wellington Ade-Ade & His (Juju) Orchestra.



JZ 6088-Owo Lowo Agbara Ko/ Abiba Alaso
" 6087-Ori Lo Yemi/Saka Ilorin Aminu Olaribigbe & His (Sakara) Band
" 6089-A Gbere Wa De/Awọn Kokokeke- Taibus Abuna & His (Apala) Band
RJZ 100-Ma Pami/Zambesi (In Afro-Cubol)
RJZ 101-Powo Ba De/Adaku (Ibo)
RJZ 102-Ma Doyinbo/Igbuem Iwem (Itsekiri) (Ibo)

*Sold by all the best stores*

**"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS**

HIS MASTER'S VOICE

*Distributed by* THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# Alapara Ibadan Nki Yin o

OKE FỌKỌ
IBADAN.

Mo ti ri ọrẹ mi Adelabu tipẹ. Ki a ma purọ akukọ ti mo ma ri niyi lati igba'i o ti ti Mẹkka de. Nkan ti o dun mi ninu ọrọ rẹ nipa, ko fi ọka ranṣẹ si mi fun Oke Arafa ti o gun na. Mo bi Ade lere nigbati a pade ni Ajọ awọn olofin Iwọ-Orun (House of Assembly) ni ijọ yi ni ilu Ibadan. O ni mo gbagbe wipe on ngba awẹ lọwọ. Bi a ba gba awẹ a nsu ẹsu. Emi ko mọ bi wọn ti nṣe gba awẹ Irugbo ṣa o.

Mo ri iyipada atata ninu iwa Alhaji Adelabu, o nhu iwa ọmọ Allah tabi bawo ni awọn Imale ṣe npe Ọlọrun?. Ọlọrun - Ọlọrun, pe Ọlọrun ni orukọ ti o wu ẹ. ODUMARE ni ẹniti o ni ọrun njẹ Yoruba ti mọ Ọlọ-run tipẹ. Ọna ti wọn fi nsin lo yatọ.

Awe, ọrẹ mi Adelabu nsin Ọlọrun nitotọ nisisiyi o Bi Ọlọrun Oke'Badan ni, bi Ọlọrun Isalẹ-Ijẹbu, bi Ọlọrun (Sango) ti ilu Ọyọ ni, tabi Binuyọ (Orisa Tapa) ni, Alapara ko mọ ikan nibẹ Emi Alapara ri daju pe ọrẹ mi, Ade, Ade, ti yipa, da si ẹelu rere.

Ade, Alhaji Adelabu, jọwọ ma gbagbe gbẹgiri mi ati ọka elubọ fun Oke Arafa ti o ti gun. Mo juba o.

IYAN ATUNGUN ỌBẸ ATUNSE

Bawo ni a ṣe wa sinu aiye yi? Ẹnikan ti o fẹran iwe mi ti mo nkọ ni ọsọsẹ ni o bere ọrọ yi lọwọ mi nipa iṣẹlẹ ọkọ Reluwe ti o ṣẹ ni eti Lalupọn ni aipẹ yi. Emi Alapara papa ko mọ nkan ti mo wa ṣe ni aiye boya iwọ ti o nka wosika mi le sọ fun wa nkan ti a wa ṣe ni aiye. Jọwọ ka iwe ikan ninu awọn obi ti ọmọ rẹ ku ninu ọkọ ti o wo lulẹ si eti odo Ọba leti Lalupọn ni aipẹ yi. Emi lo kọ si ṣugbọn nko ni da orukọ rẹ. Ka, on niyi:-

Alagba,

Ọkan mi kunfun ọgbẹ nko mọ bi mo ṣe le bere iwe mi yi si ọ. Ọmọ mẹta ni mo bi, meji ọkunrin, ikan obinrin. obinrin yen ni agba, o si gbajumọ, o si tun ni ori a nmọ iwe. Awọn ọkunrin papa ni kilo ṣubu lẹ awọn. Wọn mọ iwe de bi ti a mọ de; wọn si ni ki nfi ọkan balẹ wipe iya ko jẹ mi mọ

Alagba, eyi ẹgbọn wọn obinrin lo kọ lọ silu Ọba-o ba atakunrin kan pade, o loyun fun, o si jalejsi si ilu oyinbo. Birmingham ni orukọ ti wọn npe ilu ti o ku si. O dun mi papọ ti nko le de bi oku rẹ

Eyiti o wa ṣe mi yi lo ba mi lẹru pupọ. Awọn ọmọ mi ọkun'in mejeji ti mo fi ọkan tẹ wa ni iwe ẹri fun ile iṣẹ pataki lati lọ kọ ọkọ si ni ilu Zaria (Saria) Tẹlẹtẹlẹ nko fẹ ki wọn lọ, aitoripe wọn ti nṣe iṣẹ, awọn si ntọju mi Iya wọn ti salọ tipẹ awọn si ni alabaro fun mi. Awọn ẹbi ati ọrẹ bẹ mi pupọ wipe ki njẹ ki wọn lọ.

Ki tilẹ ni awa ṣe ninu ile aiye? Awọn ọmọ mi mejeji wa ṣe alabapade iku ojiji ninu ọkọ Reluwe ni eti Odo Ọba. Ko tilẹ si tkan ti o dun mi bi oku ati aye wọn ti nko ri.

"Alagba, kini awa ṣe ninu aiye" ? mo fẹ ki ẹ sọ fun mi sẹ kini a wa ṣe ninu aiye oṣi yi ?.

Ọrọ niyi o, ẹnyin ara mi. Emi Alapara Ibadan na ko mọ bi mo ti ṣe wa si aiye ati nkan ti a wa ṣe. Ṣugbọn mo mọ lati bọwọ fun agba. Mo lọ si Mọṣalaṣi, mo nṣe sara. Mo nlọ Ṣọṣi mo ndaka mo si ngba adura. Ẹsẹ emi na ko nyẹ ni mọṣalaṣi. Emi Alapara papa ko fi irungbọn Lemọmu jona. A ni nko mọ fi irungbọn alufa Lemọmu jona o.

Boya a leri ọkan tabi meji ninu awọn enia wa ti o le sọ nkan ti a wa ṣe n'nu aiye fun wa; ṣugbọn Alapara Ibadan ri, ni ọrọ kan iya ni awa jẹ ninu ile aiye. Tabi ? Ẹnikẹni ti o ba le sọ orukọ fun mi ẹniti ko jẹ baba nla iya ninu ile aiye ki o to jade nibẹ emi Alapara a san owo ti a npe ni ọke meji sile ati egba fun.

Kọ iwe re s... i tu, ki ri ibi ko to ku. o si daruko re a... eni na Alapara ni o di ọse ti o gbadun aiye re ti ko ti o mbọ o.

# Duke of Windsor



Ẹniti a nwo, ti o duro ni waju Gomina Sir Hugh Clifford ni oloye nla Duke of Windsor lasiko ti o mbẹ ni ọmọba alade l'u Oyinbo Gẹsi H. R. H. Prince of Wales. O wa bẹ ile Nigeria yi wo ninu ọdun 1925.

Awọn enia meji ti duro niwaju ọmọba na ni awọn ara ilu Ibadan meji ti nwọn bi wọn lọ ja ogun Kamaru ni ọdun 1918.



# EBUN NLA

## Wa je 375,000/- ninu

Orire ti o tobi julo ni EAST

Eniti o ba yege ninu orire na yio je 355,000/- eniti ila kini ati ekeji tire ba dogba po pelu tiwa yio je 20,000/-

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Şe eto awọn nọmba lati 45 si 60 ninu ojule kọkan, ti aropọ rẹ lati ọtun si osi, lati oke sisalẹ lati igun kini si igun keji yio fi jẹ 210. A ko gbọdọ lo nọmba kanna lemeji.

Ojọ ti ako ni gba iwe lọdọ ẹnikẹni mọ ni 26/10/57. Ẹ fi gbogbo iwe nyin ran ọkọ ofurufu. Asi rẹ yio jade ni 31/10/57.

| Last Result Total 206 | | | |
|---|---|---|---|
| 46 | 48 | 55 | 57 |
| 59 | 53 | 50 | 44 |
| 49 | 47 | 56 | 54 |
| 52 | 58 | 45 | 51 |

Owo ẹyọ kan 25/-. Fun mẹrin 45/- Fun mẹrin-dilogun 80/- Fun merinlelogun 100/- Fun mẹj'din'ogbọn 120/- ati bẹbẹ lo.

OFIN:- Ẹ lesa pupọ sinu iwe miran pẹlu owo rẹ ni pipe, ao gba. Ẹ le fi owo ranşe ni Iwe owo ti (Postal Order tabi Money order) Nọmba ti Gẹsi ni a fẹ.

Eniti orire tirẹ ba dọgba pọ pẹlu tiwa ni ao gba pe o yege Ẹniti o ba fẹ gbọ esi ki o fi 1/- owo ọkọ kun owo tirẹ, şugbọn bi o ba fẹ gbọ kiakia fi 2/- owo ọkọ ofurufu kun owo tirẹ. Ko si ẹjọ nibẹ, eyi ti a ba şe ni abẹ şe.

Fi owo ati orire tirẹ ranşẹ si:-

### S. C. L. CORPORATION

P.O. 12, ALIGARH (INDIA)


No. 73/S. 2/537

## Ministry Of Health-Western Region.

VACANCY FOR TEMPORARY CLERICAL OFFICERS (REVENUE COLLECTORS)

Applications are invited from retired Civil Servants (Pensioners) preferably of Western Region origin, for appointment as Temporary Clerical Officer (Revenue Collectors) in the Medical Department, Western Region Scale of Salary: D1,2,3: £150 x 6 - 198;
£207 x 9 - 258;
£290 x 12 - 360.

The rate of Salary in each case will be calculated in accordance with the rates for computing the Salaries of re-engaged pensioners.

For Further particulars and method of application please see Western Region of Nigeria Gazette No 47 Vol 6 Notice No. 948 of 3rd October, 1957.

Note: Application should be submitted as soon as possible.

No. 73/S,2/537.

## Western Region Public Service

VACANCY FOR ADMINISTRATIVE OFFICERS

Persons with legal qualifications (a call to the bar and/or registeration to practise as a Solicitor in Nigeria) are invited to apply for posts in the Administrative Class of the Western Region Public Service. Salary: Scale A: £624 x 36 - 696; £804 x 42 - 1,140; £1,188 x 48 - 1,380 Consideration will be given to perivious suitable experience in determining the commencing Salary of successful Candidates.

For further particulars and method of application, please see Western Region of Nigeria Gazette No. 47 Vol 6 Notice 942 of 3rd October, 1957.

Closing Date: Overseas Candidates 30/10/57.
All other Candidates 9/11/57.

# Ola Ng'ori Ola



**Aworan ti a nwo ninu Iwe wa yi niti Alakoso Iwe Irohin wa Councillor Taju Thompson, on ni awon Igbimo Onina-mona-mona fi ipo ola Alabojuto ati Oludamoran 'ori ise na da l'ola.**

Ọgbẹni Taju Thompson yi je ọdọmọde ti o nşe bi agbalagba, gegebi Owe Yoruba ti o sọ wipe "Ọmọ ti o ba ma je aşamu kekere li o ti şe enu şamu-şamu", be gege ni ọrọ ti Alakoso Iwe Irohin Oloyinmọmọ ti a npe ni Eleti-Ọfe yi. Ẹnikeni ti o ba mọ igba ewe re, yio fi lakaye mọ daju wipa o nilati jẹ olu tabi nla pataki nile aiye.

A fi eyi tọrọ lọdọ Ọlọrun Olodumare wipe ki o fun ni ẹmi gigun ati alafia ara ki o fi le şe akoja gbogbo rere ti Oluwa ti pase fun ati eyiti o mbọ. Amin.

### OJO TO RỌ ŞE JAMBA NI OKE ỌYA

KADUNA. A gbọ irohin wipe, iru ojo ti o rọ ni ọdun ni, ọjọ ti pẹ ti awọn ti ri iru re l'oke Ọya. A gbọ pe bi ojo na ba bẹrẹ, iwọn ọjọ meji tabi mẹta ojo na ko ni dawọ duro. Ki ti gbe?

Nilẹ awọn Hausa, bi nwọn ba kọle tan, kaka ki nwọn fi panu tabi kiriyo bo o lori, nşe ni nwọn o fi amọ rẹ pa, a yafi awọn ti o lowo lọwọ lo nfi panu bo ile wọn.

Ninu ojo ti o rọ koja lọ yi, ile mejidilọgọfa ni a gbọ wipe o wo lulẹ ati wipe ninu awọn ile ti o wo lulẹ na, ẹnikan şoşo ni aj wo lu mọlẹ, eyiyi şelẹ nigbati ojo rọ nilu Zaria. Ọpọlọpọ ọna mọto ni agbara ojo balẹ patapata tobẹ ti ko şe rin fun awọn mọto.

Ko nşe ni Oke Ọya nikan, a tun gbọ wipe nilẹ Ija - Orun, nilu Uyo, Abak, ati ni Opobo nşe ni agbara

(Wo yoko loju ewe kẹjọ)


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, [illegible] Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

# Ojo to ro se jamba ni Oke-eya

(O bere lati oju ewe keje)

ojo nya wo inu yara, nigbati Odo kan tan, o ya bo oju ona moto ti o lo lati Oron si Opobo si Aba o si gbe Kereni lo bi m bamu Awon agbagba ile na so wipe, o le ni iwon odun mekanlelogbon ti iru ojo bayi ti ro gbehin Hal are. ojo odun ni po, o le kenka.

## Ijagboro Be Sile Nilu Poland

WARSAW. Kakiri agbaiye ni a ngburo ija ogun irokeke ati ijagboro larin eya tabi awon to nso ede kanna.

Edekoyede kan be sile larin meji awon omo akeko ile Poland lori Komunisi ko se Komunisi (Communist) tobe ti awon omo ogun ilu na fi dide wipe awon yio gbeja ijoba nitori ki awon omo akeko mase ba ibajoko ijoba won je.

Awon omo akeko na bere si ju okuta nlanla si arin awon Soja, ati okufo igo, awon soja si yio agba etu ap'omolekun si arin meji won, awon omo akeko na nkigbe olele le awon soja na lori.

Awon olopa ilu na ko die ninu awon omo akeko nwonyi, awon si lo ti won mo inu ile igbimo won ti nwon ko ni petesi mejo lera won.

Ohun ti a gbo wipe o fa rogbodiyan yi sile ni wipe, Ijoba Komunisi pase wipe iwe irohin kan, eyiti awon omo akeko nwonyi ma nsoro si, ti awon fi ntako ijoba, ni Ijoba so pe ko gbodo jade mo.

Nigbati ijagboro na sele nse ni gbogbo ilu daru, moto ko ri ona gba, oko-ile (Train) ko ri ona lo, gbogbo ona lo di, lati ojo ti nwon ti nse ilu Warsaw iru rogbodiyan na ni ijagboro bayi ko sele ri.

### ALO O ALO!

I Oruku-tindi-tindi, oruku-tindi-tindi, oruku bi igba omo, gbogbo won je kiki omo agan.




## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alaj la omode agbomole bi orisa, akokoluko ogun ti nda'mo l'ekun igbona, atata ogun ti np'o tutu re werawara a je bi idan, a gba bi etu ibon. O s'abiku di ikugbagbe, o s'omo ti nhehin l'ore. Iko ri i sa, Iba ko l'ona tapiri. sipeci ri d'ekun iyonu Olugbala l'omo ti nyagbe orin o kapa inu wo, o lu jedi l'alupa, gbogbo abiyamo nyo sese, Ela ri i o roju, Orere ri i o na'gbe bo'ra, Eyi npa'iemo lodilese, ote ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye njijadu re. O de'lu Ibo, o doge, o de'le Hausa, o d'oba, gbogbo Onisegun l'o so pe ko legbe, gbogbo omode lo nfe e fun ilera.

IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4/- owo oko 1/6d fun Igo kan.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge, Street, P.O. Box 2, Ebute-Meta.


# Karosini Shell fi ilopo meta dara ju

*fun titan ina*



1 JIJO INA RE LAGBARA JU

2 O NI ALOPE

3 KI SE EFIN




***Fun ki ina mole dada julo ra***

SHELL KAROSINI


Printed and published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 4127